# IFARAHÀN ỌLỌRUN LORI OKE SINAI

## Ẹksodu 19:1-25; Heberu 12:18-25

## ẸKỌ 60 --- FUN AGBA

**KỌSORI:“Ẹ sunmọ Ọlọrun, on o si sunmọ nyin” (Jakobu 4:8).**

**I Israẹli de Oke Sinai**

1 Wọn de aginju Sinai wọn si pa agọ ni oṣu kẹta, ni ọjọ kinni, Ẹksodu 19:1, 2
2 Mose goke lọ si iwaju Ọlọrun o si gba aṣẹ wa fun Israẹli, Ẹksodu 19:3
3 A ran wọn leti gẹgẹ bi Ọlorun ti mu wọn jade lati jẹ “iṣura” fun Oun, Ẹksodu 19:4-6
4 Israẹli lọ sinu majẹmu pẹlu Ọlọrun a si fi idi ipo Mose mulẹ niwaju wọn, Ẹksodu 19:7-9

**II Imurasilẹ Israẹli fun Ifarahan Ọlọrun**

1. Ọlọrun paṣẹ fun Mose lati ya awọn eniyan naa si mimọ ni imurasilẹ fun ifarahàn Rẹ, Ẹksodu 19:10, 11
2. A fi àalà lelẹ yi oke naa ká ti ẹnikẹni kò gbọdọ fi ọwọ kan, ki o ma ba ṣegbe, Ẹksodu 19:12
3. Ẹnikẹni ti o ba fọwọ kàn oke naa, i baa jẹ eniyan tabi ẹranko, pipa ni a o pa a, Ẹksodu 19:13
4. Mose ya awọn eniyan naa si mimọ́ o si paṣẹ fun wọn lati mura silẹ fun ọjọ kẹta, Ẹksodu 19:14, 15

**III Ifarahàn Ọla Nla Ọlọrun lori Oke**

5. Gbogbo awọn eniyan wariri nigba ti wọn gbọ́ aara, manamana ati ohun ipè ti n dún kikan kikan, Ẹksodu 19:16
6. Gbogbo Israẹli n ri oke naa bi eefin rẹ ti n ru soke bi ina ileru bi Oluwa ti n sọkalẹ ninu iná, Ẹksodu 19:17, 18; Orin Dafidi 50:3
7. Ipe naa dún pẹ titi kikan kikan bi Mose ti n fi iwariri goke lọ lati lọ ba Ọlọrun sọrọ, Ẹksodu 19:19, 20; Heberu 12:21
8. A kilọ fun awọn eniyan naa ki won ma ṣe sun mọ tosi, ki awọn alufa ya ara won si mimọ́ ki wọn ma ba ṣegbe, Ẹksodu 19:21-25; Heberu 12:14, 29

**IV A Fi Oke Sinai ati Oke Sioni we ara Wọn**

9. A ran awa Onigbagbọ́ leti ifarahan Ọlorun ni Sinai bi o ti lẹru lọpọlọpọ tó, Heberu 12:18-21
10. Ṣugbọn awa wa si Oke Sioni, Jerusalẹmu ti ọrun, ilu Ọlọrun alaaye, Heberu 12:22
11. Awa wa si ijọ akọbi, si ọdọ Ọlorun Onidajọ ati Jesu Alarina, Heberu 12:23, 24
12. Bi awọn wọnni kò ba bọ́ nigba ti wọn kọ Mose ẹni ti o sọrọ ni aye, awa o ti ṣe bọ́ bi a ba kọ Ẹni ti o n sọ̀rọ lati Ọrun, Heberu 12:25; 1:1, 2; Johannu 1:17

## ALAYE

### Ofin

Lẹẹkọọkan, ibalo Ọlọrun, pẹlu eniyan maa n mu iyipada nla wá ninu itan igbesi aye ọmọ eniyan. Ohun iranti nla ni ohun ti o ṣẹlẹ nigba ti Ọlorun fi ọwọ́ Rẹ̀ ṣe amọna awọn Ọmọ Israẹli jade lati Egipti, kuro ni oko-ẹru, nipasẹ orișirịși ịșẹ-iyanu nla nla. Bakan naa pẹlu ni o tun jẹ iṣẹlẹ nla nigba ti O mu wọn wa si iju Oke Sinai nibi ti Mose ti pade Ọlorun ni oṣu diẹ sẹhin nibi ti igbẹ́ ti n jo. Nitori pe nihin ni Israẹli yoo gbe gba Ofin alai labuku ni lọwọ Mose, nipa eyi ti Onipsalmu kọrin bayi:

**“Ofin OLUWA pe, o nyi ọkan pada: ẹri OLUWA daniloju,**
**o n sọ ope di ọlọgbọn.**
**“Ilana OLUWA tọ́, o nmu ọkàn yọ̀: aṣẹ OLUWA ni mimọ́,**
**o nṣe imọlẹ oju.**
**“Ẹ̀rù OLUWA mọ́, pipẹ ni titi lai, idajọ OLUWA li otitọ,**
**ododo ni gbogbo wọn.**
**“Nwọn ju wura daradara pupọ; nwọn si dùn ju oyin lọ,**
**ati riro afara oyin.**
**“Pẹlupẹlu nipa wọn li a ti ṣi iranṣẹ rẹ leti; ati ni pipamọ**
**wọn ere pupọ mbẹ” (Orin Dafidi 19:7-11).**

### Igba Ofin

Igbà titun ni o bẹrẹ pẹlu fifun ni ni Ofin yi, eyi ti o n fi ifẹ mimọ́ Ọlorun hàn, ki i ṣe kiki fun Israẹli nikan ṣugbọn fun gbogbo agbaye, ki Ofin gẹgẹ bi olukọni ba le mu awọn eniyan wa sọdọ Kristi, Olugbala ti a ṣeleri, ti O mu adura nla ni sẹ̀, “Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi ti ọrun, bẹni li aiye.”

Ko yẹ ki o ya wa lẹnu, nigba naa, pe fifun ni ni Ofin wáyé pẹlu mànàmáná, aara, ati iro ipe ti o dún kikan kikan fun igba pipẹ, eyi ti o mu ki gbogbo awọn eniyan naa ki o wariri, ati Mose paapaa lati bẹru ki o si wariri. Nitori pe awọn ami wọnyi n kede ifarahàn Ọlọrun Olodumare tikara Rẹ̀ lori oke ti n rú ẹẹfin nì, wọn n fi hàn iru idajọ ti o lẹrù ti yoo wa sori gbogbo eniyan ti o ba rú Ofin ti Ọlọrun n fẹ lati fi ọwọ Oun tikara Rẹ̀ kọ.

**Majẹmu Israẹli pẹlu Ọlọrun**

Nigba ti Israẹli de si ẹba Oke Sinai lẹhin irin-ajo pupọ, ti wọn si pa àgọ́ wọn, ni ọjọ keji, Mose goke lọ si iwaju Ọlọrun o si mu ọrọ wọnyi pada wá: "Ẹnyin ti ri ohun ti mo ti ṣe si awọn ara Egipti, ati bi mo ti rù nyin li apa-iyẹ idi, ti mo si mu nyin tọ ara mi wá. Njẹ nisisiyi, bi ẹnyin ba fẹ gba ohun mi gbọ nitõtọ́, ti ẹ o si pa majẹmu mi mọ́, nigbana li ẹnyin o jẹ iṣura fun mi ju gbogbo enia lọ: nitori gbogbo aiye ni ti emi. Ẹnyin o si ma jé ijọba alufa fun mi, ati orilẹ-ède mimọ́." "Gbogbo awọn enia na si jumọ dahun nwọn si wipe, ohun gbogbo ti OLUWA wi li awa o ṣe." Bayi ni Israẹli ba Ọlọrun da majẹmu ti o lọ́wọ̀ ni Oke Sinai.

**Imurasilẹ Israẹli fun Ifarahan Ọlọrun**

Iṣisẹ ti Israẹli yoo tun gbe tẹle eyi ni imurasilẹ fun ifarahan mimọ́ Ọlọrun lori oke naa. Lati ṣe eyi Ọlọrun wi fun Mose pe, "Tọ́ awọn enia yi lọ, ki o si yà wọn si mimọ́, li oni ati li ọla, ki nwọn ki o si fọ aṣọ wọn. Ki nwọn ki o si mura de ijọ kẹta: nitori ni ijọ kẹta OLUWA yio sọkalẹ sori Oke Sinai."

Ipa ti a yan fun Mose ati awọn eniyan wọnyi lati ṣe jẹ apẹẹrẹ ti ode-ara fun iwa-mimọ́ ti inu ti Ọlọrun beere, "li aisi eyini kò si ẹniti yio ri Oluwa," ati nipasẹ eyi ti awọn Ọmọ Israẹli yoo fi le "ri idi ifẹỌlọrun, ti o daa, ti o ṣe itẹwọgbà, ti o si pé," eyi ti a fi han ninu Ofin ti a fẹ fi fun wọn. Nitori naa ọkàn ti a ti dalare, apẹẹrẹ eyi ti idasilẹ awọn ọmọ Israẹli ni Egipti jẹ, ni ipa kan ti yoo ṣe ninu iṣẹ mimu ni lọ si pipe eyi ti Ọlọrun ti ṣeto silẹ fun un – o ni lati jọwọ ohun gbogbo ti o ni ni ifara-rubọ fun Oluwa, ki a ba le sọ ọ di mimọ́ patapata: "Nitorina mo fi iyọnu Ọlọrun bẹ̀ nyn ará, ki ẹnyin ki o fi ara nyin fun Ọlọrun li ẹbọ ãye, mimọ́, itẹwigbà, eyi ni iṣẹ isin nyin ti o tọ̀na. Ki ẹ má si da ara nyin pọ̀ mọ́ aiye yi: ṣugbọn ki ẹ parada lati di ditun ni iro-inu nyin, ki ẹnyin ki o le ri idi ifẹ Ọlọrun ti o dara, ti o si ṣe itẹwọgbà, ti o si pe" (Romu 12:1, 2).

Nitori naa ohun ti o ṣẹlẹ lori Oke Sinai yi jẹ kokó nla kan, ki i ṣe ninu itan igbesi-aye awọn Ju nikan, ṣugbọn lẹhin eyi ninu itan gbogbo idile aye, nitori israẹli ni a fi ọ̀rọ̀ ijinlẹ Ọlọrun fun lati fi fun araye. Awọn akẹkọ́ Bibeli, ti woǹ ti ṣiro awọn iṣẹlẹ ti o ṣẹlẹ ti a mẹnu kan ninu ori ẹkọ yi, gbagbọ́ pe Ọlorun fara hàn ni ori oke naa nigba ti o di aadọ̀ta ọjọ lẹhin Irekọja ti a ṣe ni Egipti ni alẹ ti a da Israẹli silẹ kuro ninu igbekun. Nitori naa iṣẹlẹ nla yi lori Oke Sinai ni wọn gbagbọ́ pe o n tọka si Pẹntekọsti.

**Oke Sinai ati Oke Sioni**

Paulu Apọsteli ninu Episteli rẹ si awọn Heberu n ran wa leti pe akoko ti a n gbe ni igba ooe-ọfẹ yi jẹ akoko ti o lewu ju akoko ti awọn Ọmọ Israẹli la kọja ni igba Ofin lọ. Ni tootọ wọn wariri nigba ti manamana ati aara fa oju ọrun ya, bẹẹ ni iro ipe ti o n dun kikankikan fun igba pipẹ, nigba ti Ọlọrun Olodumare fi ara han lori oke nibi ti eefin ti n rú soke. Mose tikara rẹ paapaa ni, "Ẹru ba mi gidigidi, mo si wariri."

Apọsteli naa ran wa leti pe "Ṣugbọn ẹnyin wá si oke Siuoni, ati si ilu Ọlọrun alãye, ti Jerusalẹmu ti ọ̀run, ati si ẹgbẹ awọn angẹli ainiye, si ajọ nla ati ijọ akọbi ti a ti kọ orukọ wọn li ọ̀run, ati sọdọ Ọlọrun onidajọ gbogbo enia, ati sọdọ awọn ẹmi olõtọ enia ti a ṣe li aṣepé, ati sọdọ Jesu alarina majẹmu titun, ati si ibi ẹ̀jẹ̀ ibuwọn ni, ti nsọrọ ohun ti o dara ju ti Abẹli lọ."

Nigba naa bi o ba jẹ pe Israẹli, ẹni ti o kọ ẹni ti o n sọrọ ni aye – a ni Mose olufunni ni ofin -- kò bọ́, bawo ni awa o ti ṣe la a bi a ba kọ Ẹni ti n sọrọ lati Ọrun – ani Jesu Olufunni ni iye? Lai pẹ O tun n pada bọ; O si n bọ wa, ki I ṣe gẹgẹ bi Onirẹlẹ ara nasarẹti, ṣugbọn gẹgẹ bi Onidajọ fun gbogbo aye. "Awọn ọba aiye ati awọn ọlọlá ati awọn olori ogun, ati awọn ọlọrọ̀ ati awọn alagbara, ati olukuluku ẹrú, ati olukuluku ominira, si fi ara wọn pamọ́ ninu ihò-ilẹ, ati inu àpata ori òke; nwọn si nwi fun awọn oke ati awon apata na pe, Ẹ wó lu wa, ki ẹ si fi wa pamọ́ kuro loju ẹniti o joko lori itẹ́, ati kuro ninu ibinu Ọdọ-agutan na" (Ifihan 6:15, 16). "Ohun ẹ̀ru ni lati ṣubu si ọwọ́ Ọlọrun Alãye."

**AWỌN IBEERE**

1 Kin ni ṣe ti awọn ọmọ Israẹli dó nigba ti wọn de Oke Sinai?
2 Kin ni iriri ti Mose ti ni nigba kan ri lẹba oke yi?
3 Ipo oye wo ni a fi fun Mose nigba ti israẹli de oke yi?
4 Kin ni a pàṣẹ fun Israẹli lati ṣe ni imurasilẹ de ifaahan Ọlorun?
5 Kin ni imurasilẹ yi n ṣe apẹẹrẹ rẹ, kin ni Ọlọrun si n beere lọwọ wọn ni ti inu wọn gẹgẹ bi imurasilẹ?
6 Bawo ni imuasilẹ yi ṣe ran wọn lọwọ nipa ti Ofin yi ti Ọlọrun fẹ lati fun wọn?
7 N jẹ ẹnikẹni ha wa ti o lagbara lati le pa Ofin mọ́ to bẹẹ ti yoo fi mú igbala wa fun un?
8 Kin ni iṣẹ Ofin nipa idalae nipasẹ Kristi?
9 Kin ni ṣe ti manamana ati aara ati iro ipe kọkọ wá ṣiwaju fifun ni ni Ofin?
10 Kin ni kókó Ofin Mose gẹgẹ bi a ti fi fun ni ni Oke Sinai?